LIBRARY
28 FEB 1966


# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,697 MONDAY, FEBRUARY 14 1966 (2D)


## Egbewa Merindinlogun Ponun fun Ile Iwosan

ILESHA:- Ni ojo Abameta ti işe ojo kejila oşu yi ni Ijoba Ologun şe iranlowo owo eyiti iye re je egbewa merindinlogun ponun (£32,000) f'a şi ile Iwosan ti Ijo Olorun ti a npe ni Wesley "Guild Hospital" Ilesha lati ñ ma bo eto akoso Ile Iwosan na lo ati pe ki awon chunti ko si nicu ile Iwosan le wa ki o si dabi awon Ile Iwosan to wa ni Orile ede Naijiria.

Ninu Irohin to jade lati owo oga agba awon Dokita to wa ni Ile Iwosan na Dokita C. A. Peason şe alaye pe iranlowo owo ti Ijoba Ologun şe fun Ile Iwosan na bayi yio jeki ile Iwosan na ma fun awon omode ni itoju ofe ati pe awon omode lati omo owo titi de omo odun mejidinlogun ni ile Iwosan na y o ni anfani lati ma fun won ni itoju ofe lai san owo kankan.

Dokita C. A. Peason tun şe alaye pe eto itoju ofe na si ti bere lati ojo Aje ti işe ojo kerinla (oni) oşu yi ati pe ni ojo keji ti nwon şe odun Keresimesi ni awon Alakoso ile Iwosan na da eto Itoju ofe ti nwon ti ma ofun awon omode duro nitoripe awon egbe oşelu to nşe akoso Ijoba Ipinle Iwo Orun lasiko na kuna lati fun ile Iwosan na ni iranlowo ti nwon so pe nwon yio fun won tele ati pe eleyi lo mu ki eto itoju ofe daduro fun awon omode titi de omo mejidinlogun.

# IJOBA D'AWON ADAJO KOTU IJOBA IBILE DURO!

**IBADAN:— A gbo sogbanu ni agbayanu Irohin kan ti o kan gbogbo enia, ku u, ni opin ose ti o koja lo yi je fun gbogbo enia, nigbati nwon gbo wipe, Gomina Ologun Ipinle Iwo Orun Naijiria, Ogagun Francis Adekunle Fajuyi ti paşe wipe ki Ijoba da gbogbo awon adajo Kotu Ijoba Ibile yika gbogbo Ipinle Iwo Orun Naijiria duro.**

Oniwe Irohin wa ni Ibadan şe alaye wipe, Ijoba Ologun Orile ede Naijiria ti so ninu Iwe Ikede Ijoba kan fun Ipinle Iwo Orun ni Ibadan ni ale ana ojo Aiku t i işe ojo ketala oşu yi wipe, Ijoba ti yo gbogbo awon adajo kotu Ijoba ibile yika gbogbo ile ejo Ipinle Iwo Orun ni işe, nwon si d a gbogbo won duro patapata.

Irohin na tun şe alaye siwaju pelu, wipe, gbogbo awon adajo Kotu na ti nwon wa ni ipo kini, ipo keji ati onipo keta n i Ijoba Ologun ti da duro lati oni, ojo Aje ti işe ojo kerinla oşu yi.

A gbo pelu wipe, gbogbo awon Oloye ati awon enia saraki—saraki ti nwon ti je ala ga ati omo Ile Igbimo Ijoko Ile ejo na ni Ijo ba Ologun ti da duro patapata, kuro ni enu işe ti gbogbo won ko si tun gbodo de ile ejo na mo lati owuro yi lo.

Ninu Iwe Ikede Ijoba na, Gomina O log u n Ijoba Ipinle Iwo Orun Naijiria Ogagun Adekunle Fajuyi şe alaye sinu Iwe na pe Ijoba Ologun fe şe atunşe eto ati ofin Idajo ti awon adajo na nlo lowo yi, ki awon si to le şe eto ofin ati idajo awon ile ejo na, awon yio koko da a w o n adajo duro na.

Nigbati Ijoba ba da awon adajo ati awon alaga ijoko ile ejo na duro na, nwon yio wa şe atunşe awon eto ati ofin ti awon adajo na nlo patapata ni ona ti awon enia orile ede yi nfe ti yio si wulo fun gbogbo won pelu.

Bakanna ni olola Adekunle Fajuyi tun şe alaye siwaju ninu oro re pe, Ijoba Ologun y o tun şe eto lati mo agbegbe melo lo ye ni Ipinle na lati ni ile ejo fun ati iru ile ejo wo lo ye fun awon enia na lati ni.

Olola Adekunle Fajuyi tun şe alaye ninu Iwe na siwaju wipe, ni gbati Ijoba Ologun ba pari eto na, Ijoba yio tun şe eto ni ona keji iru awon enia wo lo to ti o si tun ye lati yan gegebi Adajo sinu awon ile e j o na ti nwon yio si ma a şe idajo nibe.

O tun so pelu, gegebi afikun ninu oro re wipe, awon ti awon ba mo nipa ofin daada ni

Wo Oju Ewe Keta

# Asoju Ijoba Be Alaga Wo

EKO:— Lenuiol yi ni Olola Dokita Branko Karapandza, eniti işe Aşoju Ijoba Orile ede Ile Yugoslavia ni Naijiria şe ibewo lo si ile işe Ijoba Ibile Eko ti o si lo ri Ogbeni G O Dawodu, eniti işe Alaga ile Igbimo Aşofin Ijoba Ibile Eko.



Oniwe Irohin wa Fjongboro ti o wa nibiti nwon gbe nşe abewo ni ojo na fi ye wa wipe, inu Dokita Branko dun lopolopo l a t i ri Alaga Ijoba Ibile Eko.

Nigbati awon mejeji si ri ara won, pelu ayo ati inu didun ni awon fi ki ara won, ti nwon si gba ara won lowo pelu.

Awon mejeji ijo soro lori oi nkan ti şe nlo larin Orile ede Naijiria ati Orile ede Yugoslavia, ati iru Iranlowo ti Ijoba Yugoslavia yio şe fun Ijoba Naijiria ati awon Orişirişi Iranlowo ti Ijoba na ti şe sehin fun Ile Naijiria.

WO OJU EWE KEFA

# YẸYẸNATU

## Oniyẹyẹ Ẹko

Olotu:- Yẹyẹnatu, kini ṣe iwọ ati ọrẹ rẹ ?
Yẹyẹnatu:- Ewo ni ?
Olotu: Wulemọtu
Yẹyẹnatu: Ha, ẹ mi da lohun, o jare
Olotu: Kini o wa fa ija yin kẹ ? Ṣebi ọrẹ ni ẹ pe ara nyin
Yẹyẹnatu: O ya Ọdẹ ni- O ya sugọmu alate nla ni
Olotu: Kini o ṣe ṣe ?
Yẹyẹnatu: Ohun to ṣe ko tiiẹ ṣe e gbọ
Olotu: Ṣe o ba Ọkunrin mi silọ ni ?
Yẹyẹnatu: Bi o ba tiiẹ ṣe iyẹn ni iba dara. Ko kuro ni'le ọkọ, to ṣe aya ọkọ, ko kuro nibi iṣẹ ko ri owo gba
Olotu: Kini de ?
Yẹyẹnatu: Ṣe ẹ mọ pe Akintọla ni ọkọ rẹ nijẹ ?
Olotu: Yẹs, bẹni
Yẹyẹnatu: O lọ fi si Iwe Irohin pe on ko jẹ Wulemtu Akintọla mọ
Olotu: Ha ! o kọ ọkọ rẹ niyẹn
Yẹyẹnatu Ẹ wi bẹ
Olotu: Kini ọkọ rẹ wa ṣe ?
Yẹyẹnatu:- Nigbati nwọn wi fun iyẹn ko kọkọ gbagbọ nitoripe awọn mejeji jẹun pọ ni owurọ ọjọ ti o yọ ninu Iwe Irohin
Olotu: Lootọ?
Yẹyẹnatu: Were ni nwọn ba gbe iwe Irohin si iwaju rẹ. Bi o ti ri I, o lanu pako ko si pade titi eṣinṣin fi ko si lẹnu
Olotu; O maṣe o. O ya a lẹnu gan ni
Yẹyẹnatu: O ya emi na lenu kẹ Nigbati o dele o bere lọwọ Wule
Olotu: Hahẹn, kini Wule wa wi?

Yẹyẹnatu: O ni igbati on ri gbogbo awọn ti njẹ orukọ ọkọ on ti nwọn nparọ orukọ n on ba lọ parọ ti on na
Olotu: Ti tani o wa parọ t'rẹ si?
Yẹyẹnatu: Ti baba rẹ ni.
Olotu: Kini ọkọ wa wi?
Yẹyẹnatu:- Ọkọ ni ki o ka lọ ba ọkọ rẹ titun
Olotu:- Tani iyẹn?
Yẹyẹnatu:- Baba rẹ ni kẹ
Olotu- O maṣe o, kini o wa ṣe o?
Yẹyẹnatu Lo ba wa ba ni ki nba on bẹ ọkọ on.
Olotu Bawo nibi Iṣẹ rẹ tiji?
Yẹyẹnatu- Nigbati nwọn gbe iwe ti nwọn fi nsan wo de, orukọ Wule ati jọ ni o wa nibẹ, nigba ti o wa fẹ fọwọsi iwe owo, o kọ orukọ titun, ni akọwe ti nsanwo ba ranri pe on ko le fun ni owo na.
Olotu Nitoripe orukọ ti o njẹ nigbana yatọ si eyi ti o wa lori iwe tan?
Yẹyẹnatu Yẹs kẹ, o ni kini ki on ti ṣe e ?
Olotu O tun kọ iyẹn wa ba ọ? o ro pe ọlọgbọn ni iwọ ṣa ?
Yẹyẹnatu emi ki iṣe ọlọgbọn ni? loju tiyin mo le jẹ omugọ ṣ gọgọ to ju awọn ti ... ugọ ile, mọto ati ilẹ ni ato kọ ẹhin si wọn kele pe mi Ọdẹ.
Olotu: Ṣebi awọn Ọdẹ bi iwọ ba ni ?
Yẹyẹnatu; emi Ọdẹ. Ẹ ku ṣoko o, Ọlọgbọn
Olotu: Ṣebi o ṣe nfi mi ṣe yẹyẹ ni igba kan ni yẹn pe emi Olotu tiko le gbe Ikoyi...
Yẹyẹnatu Ẹ ma gbe iyen wa O, Ọl—uti—lọ ni Oyinbo npe ni by-gone is by—gone' ohun to lọ ti lọ
Olotu: Ṣe o wa gba nisisiyi pe emi gan ni Olotu ?
Yẹyẹnatu: Olotu ni emi na

Wo Oju Ewe Kaiun

# Itumọ Orukọ Aguiyi Ironsi

Lati Owo S. O. AKORE Ifo



**Oga'gun Aguiyi Ironsi**

A — Ajanaku o l'ekan Ọba ti o merin so ko jẹ
G — Gudugudu ki ṣẹgbẹ dundun
U — Urah Olugbala gbogbo nyin de
I — Iṣbayi ni a o ma a fi ru iti wọle
Y — Ya epo kuro lara alikama ati ewurẹ lara Aguntan
I — Iwọ ni mo yan ni Olurapada fun wọn

I — Igba ati akoko rẹ yio tu Orilẹ-ede na lara.
R — Ran mi, Iṣẹ Rẹ ni Oluwa
O — Oluwa nṣiṣẹ iyanu ona ara ni Iṣẹ Rẹ.
N — Ni ọwọ rẹ ni ao ti gba Ọpọ la,
S — Sin wọn la aginju na ja, gba wọn lọwọ Ọta wọn
I — Iwọ ni yio mu wọn de ilẹ Ominira.

# Ni Iranti Ọgbẹni Lenin



Aworan oke yi ni ti ile ti awon enia ile Rosia ati Kuba ti ma nṣe ipade ni Moscow ti iṣe Olu Ilu Rosia,

Ijọba Orile—ede ile Rosia ko ile yi fun Iranti Ọgbeni V I Lenin eniti o ja fun Ominira Orile—ede ile Rosia ki awon enia na to gba Ominira ninu ọdun 1917

Ṣugbọn ohunti o ya enia lenu ninu aworan ti e nwo lo ke iwe yi ni wipe ni nu oko ofurufu kan ni nwọn ti ya aworan no

## Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

# A Dupẹ Lọwọ Ijọba Ologun

Olotu, Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati dupẹ lọwọ Ijọba Ologun ilẹ Naijiria ati papa julọ Gomina ologun agba fun apapọ Ijọba Naijiria Ọgagun J. T. U Aguiyi Ironsi nipa ore nla to ṣe fun awa mẹkunnu to jẹ ọmọ ilẹ Naijiria nipa awọn oṣelu ti wọn jẹ wa niya eyiti nwọn tun sọ iṣẹ iṣelu di owo ati oye idile wọn.

Eleyi jẹ ọpẹ nla fun awa olugbe ilẹ Naijiria ti awọn ọmọ ogun gba silẹ lọwọ ajala ti awọn oṣelu gbe bọ wa lọrun, lẹhinna mo dupẹ fun gbogbo awọn Ọgagun to wa fun ipinlẹ kọọkan ati pe adura mi ni pe ki Ọlọrun Ọga ogo



Ọga'gun Aguiy Ironsi
Olori Ijọba Ologun Ilẹ Naijiria

tan wọn lọwọ, nwọn ko ni ṣe iṣẹ na ti, amin,

Mo tun bẹ Gomina ti Ipinlẹ Ariwa Ọgagun Hassan Katsina ki o jọwọ gba wa nipa iya to ti jẹ wa sẹhin ni ilẹ Igbomina ati pe akoko iya na ni owo ori eyiti iṣe ọna meji ni a ti nsan owo ori eyiti ao san owo ori ni Eko ti ao tun san ni ilẹ Igbomina.

Ninu ohunti a tun nfẹ nipe ki ilẹ Igbomina le di ominira eyiti a o fi duro gedegbe, a ti tun fẹ ki Gomina na tun ṣe iranlọwọ bi awọn nkan ilọsiwaju yio fi de ilẹ na gẹgẹbi ọna ti nwọn yio fi da ọda si, ile Iwosan, ina mọnamọna ati ẹrọ omi.

Olotu, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi, ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o.

Emi ni

Alufa Y. A. Aiyelogbọn Ajejọla

Alasẹ Ipo

## Mo Ki Balogun Fajuyi

Mba sope bi Olotu gbajumo iwe Irohin-Imole yi ba le gba mi ni aye ninu iwe Irohin re oloyin momo lati kan saara si Ogagun Adekunle Fajuyi ti ise Gomina Ologun fun Ipinle Iwo Orun Naijiria lori awon iṣẹ nlanla ti o ti nse fun ipadabo alafia ati idagbasoke ni kiakia si Ipinle Iwo Orun Naijiria.

Gere ti Fajuyi bo si ori aga Ijoba ni o pasẹ ṣiṣi awọn omi erọ ti Ijọba ana ti ti, bakanna ni o tun ṣe ofin pe ki awọn Ijọba Ibilẹ san owo oṣu awọn Ọba ti Akintọla so owo won di kọbọ lọ'dun ati ọpọlọpọ miran ti o ṣe pe awa mẹkunnu ti nkigbe fun lati nkan bi Ọdun merin ti Ijọba tipatipa ti wa ni Ipinlẹ yi.

A ki Ọgagun Fajuyi ku Iṣẹ o Oluwa yio ma dari rẹ si ọna rere o. Eledumare yio si ṣe alatilẹhin rẹ o. Iwaju ni o ma lọ o.

Emi ni

Musibawu Akintunde
IGBO—ỌRA.

## A Dupẹ Lọwọ Ọgbẹni Dawodu

Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati dupẹ ọwọ alaga Ijọba ibilẹ ilu Eko fun ikede to ṣe laipẹ yi pe nwọn ko ni sọ ọdun mejọ ti nwọn lo ni ile ẹkọ ilu Eko di ọdun mẹfa gẹgẹbi irohin ti a kọkọ gbọ ninu ọdun to kọja lọ yi

Eleyi jẹ ohunti o ba awa obi ọmọ ninu jẹ nigbati a gbọ ikede pe nwọn yio sọ ile iwe ti ilu Eko di ọlọdun mẹfa eyiti awa Obi ko si fi ara mọ lati jẹki Ijọba ṣe eto ti ko le ṣe iranlọwọ kankan fun awọn ọmọ wa lẹhin ọla.

Otitọ ni Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria sọ ile iwe ti Ipinlẹ na di Ọlọdun mẹfa ṣugbọn eto ti awọn Olukọ ngba kọ awọn ọmọ ni Ipinlẹ na yatọ si ti ilu Eko,

Nitori eyi awa Obi dupẹ gidigidi lọwọ Ọgbẹni Ganiyu Ọlawale Dawodu fun eto ti o yara ṣe nigbati o de ori aga gẹgẹbi Alaga Ijọba Ibilẹ ilu Eko na

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ẹ ko ni si ọrọ tẹ o. Amin

Emi ni
S. Jagunna

EKO.


# Iwe Itaja 1966

Idamu owo ha wa fun ọ bi
Abiku ha nyọ ọ lẹnu bi
Airi iṣẹ se ha wa fun ọ bi
Ailera mba ọ ja bi
?

Iwọ le bọ ninu gbogbo wahala aiye wonyi ti iwọ ba ra ninu awọn ohun Ijinlẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ti a to lesẹsẹ si isalẹ yi.

1 Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/— di 22/6
2 Iwe Afọsẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 4/6 di 3/6
3 Iwe Itumọ Ala ati Ogun Wibẹjẹbẹ 4/6 di 3/6
4 Iwe Egbogi Awogba Arun 20/— d 17/6
5 Iwe Ilana Ifa Yanrin titẹ ati etutu ṣiṣe 20/- di 17/6
6 Gbedegbẹyọ Hausa 3/—
7 Iwe Aniyan Irun 2/— di 1/—
8 Turari Iṣegun Ajẹ ati Itaja 10/6 Pangolo 2/6 paketi

Fi Owo ranṣe si
J, O, SAOYINKA
P, O, Box 159
MUSHIN

tabi

9, Iyala Street Oduabọrẹ, Mushin

# KERE O! KERE O!!

## Awọn Tani Wọnyi ?

AWỌN ỌMỌ ODUDUWA MẸTA TO JOYE 'ỌNI' TẸLE ARA WỌN



LATI ỌWỌ OSI:- ỌNI ADELẸKAN (Olubuse) ẸNIKEJI:- ỌNI ADEMILUYI (Ajagun) ẸNIKẸTA ỌNI ADERẸMI (Atọbatẹle)

ITAN WỌN DUN KA

Njẹ o ti ka ninu itan Igbesi aiye Oduduwa ati ti awọn ọmọ rẹ" to ṣẹṣẹ jade?

Bi o ko ba ti ra a, maṣe jafara, ni'oripo, bi awo ran awọn "ỌNI" mẹta yi ti ṣe jẹ ohun iyanu ta ti le ri wọn papọ, bẹni itan wọn rẹ ninu iwe na.

Maṣe jẹ ki nwọn ro hio rẹ fun ọ, Tete lo ra tire koto tan, 3/- pere ni, Post age 9d

F'owo tirẹ ranṣẹ si:—

ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria.

(Leti eja Ikokare)

## FI EYI KOGBON

# Ibinu Ki Imu Ire Wa

**Lati Qwo S. A. Fatolu, Ibadan**

Obinrin oloro kan wa ti o ni omo odo pupo, ekan ninu won a ma a tu irun abiya fun un lale ki o to sun.

Ni ojo kan bi omo o do Obinrin yi ti ntu irun abiya re fun un o sesi fa irun abiya re ya, o se bi irun ni on nfa. Lehin iseju die abiya bere si ta Obinrin yi. Nitorina o fi owo fa abiya re.

Bi o ti fi owo kan an eje ni o fi owo ra. o si fi ibinu wipe, "Ha. Adeoti, mo ni ki o se mi loso o si se mi lose ?

Nigbati Adeoti gbo bayi kaka ki o bebe erin ni o bu si eyi si mu ki obinrin yi pa giri lati mu Adeoti eyi ni ti tese-te, sugbon sibe na pelu ibinu yi ni obinrin oloro na sare lee.

Bi o ti nle lo, iko fi ese ko ti o si subu lule to be ti o fi daku. Opolopo owo ni awon enia re na ki obinrin oloro na to tun soji. Lati ojo na lo ko tun je sanso be soro mo.

Iwo ti o nka iwe yi fi eyi kogbon ki o si ranti owe baba wa ti o wipe, Ibinu ko da nkan, suru baba iwa, agba to ni suru ire gbogbo lo ni ati pe a ki le ekute ile sa ni ki a fi apa se.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 21 Fep 18) Ero idunnu kan yio wa fun o loni, sugbon so arare ki idunnu na ma pada di ibanuje fun nikehin, E so di owo re,

PISCES (Feb19 March 20) Sora pelu awon oro ti yio ma jade lenu re ni owuro yi, ki o si ma se pele pele, nitoripe ewu kan wa ni ona re loni.

ARIES (March 21 April 20) Gbogbo ohunti o ba se loni ni yio maa yori si rere, sugbon sora gidigidi ki o ma ba se si oro, so ni irole yi, ki awon enia daru kan ma ba se ri tire so

TAURUS (April 21 May 11) Ojo oni dara fun o, lati de odo awon olufe re, gbogbo oro ti o ba si so ni yio je itewogba nitoripe ife ti yio ni si ni oni ju ti atehin wa lo.

GEMINI (May 22 June 21) Gbogbo awon ohunti o ba fe se loni, lo ogbon inu re lati se won nitoripe ogbon inu ni ejo nio

CANCER (June 22 July 22) Gbogbo awon ohunti o ba da owo le loni ni yio yori si rere, sugbon sora pelu oro ti yio maa jade lenu re loni, nitori awon abinu eni

LEO (July 23 Aug 23) Ogbon inu re ni ki o maa lo loni ma si se ba enia kan ko egbe papo ki nwon ma pa se ye imo an re yato si ohunti o fe se

VIRGO (Aug 24 Sept 23) Awon enia kan yio se iranlowo fun o loni ti yio ri fi okan re bale ninu gbogbo ohunti o ba nse, nitorina, ma yaju si enikan

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Iru rere re yio gba o ko olori ekan loni ti yio mo iyi ise ti o nse ni ona ti yio fi yin o ni ona ti yio mu awuri wa fun o

SCORPIO Oct 24 Nov 22) Iwo yio ri ebun nla kan gba lowo enikan ti o mo iyi ati imore ise re loni bo gbo enia lo ngbadun ise owo re, ma e yaiwa re pada,

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Iwo yio ri irohin ayo kan gba loni ti yio mu inu re dun, bee ni gbogbo nkan ni yio si dara fun ni ale o loni

CAPRICORN Dec 22 Jan 21) Ogbon inu re ati iwa pele yio jeki o se aseyori loni ninu ohun kohun ti o ba da wole lati se

BERE FUN OJULOWO EGBOGI—

## "Congreve's Iodo Form—Oinment"



Atamatase ni egbogi" ADI-ELEGBO" yi je fun itoju gbogbo orisirisi "EGBO—ESE" ni kiakia bi o ti wu ki jo re ti le pe to, Adielegbo yi ko ni egbe nipa wipe awa ko idoti ni bi eri gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lehinna oju egbo yi o ba ji sinu yio jeki oju re hu wa soke, yio si pon daradara tun bakanna ko si mo aerewere ni yio si san patapata Alafia de si o niyen :

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won abssale iwe yi ni ogbe ranse lo ra. Bibeko awon Elere ibu on ijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o mase gba rarao

Waterloo Medicine Stores
8 PalmChurch Street Lagos
22878 Lagos Nigeria (Ola Iya Fanji)
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos

## Ha Kini Eleyi




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN META

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupo A ni O dara jui gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lo.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun re si dara pupo ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lo. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun,

Tete lo ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant Brand coils tire loni, ki o si danwo; iwo yio ri bi o tise pa gbogbo yanmuyanmu inu ile re ti iwo ati awon omo re yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu ori erin meta ni nwon mu fun o

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni subu lo itaja kakiri orile ede yi

Distributor

AMOS GBENLE & BROTHERS
34: Docemo Street Lagos.
6 & 11 Balogun Street West

# Adebo Lo Si Paris

EKO Ni ojo ojo'Ru ti ise ojo kesan osu yi ni Oloye Simeon Adebo to je asoju fun ile Naijiria ninu ajo Igbi mo agbaiye ba oko ofurufu fi ilu Eko sile lati lo ba won se ipade kan eyiti ise ti awon Asoju fun ile ifi owo pamo ti ajo orile ede agbaiye eyiti nwon yio se ni ilu Paris.

Oloye na ni o je asiwaju awon Asoju ile Naijiria ti o ba won lo se ipade na ninu awon enia ti yio lo se asoju fun ile Naijiria ni Dokita Pius Okigbo, ogbeni F C Ogbu to je Akowe agba fun ile ise minisita alamojuto eto owo fun apapo Ijoba ile Naijiria.

Opolopo enia jankanjan kan ninu awon osise ile ise Ijoba apapo ile Naijiria lo pese si ibudo'ko ofurufu la ti lo dagbere fun won.

Oloye Adebo fi ye oniwe irohin pe on yio pada si New York lehin ti nwon ba pari ipade ti nwon lo se ni Paris lati ma ba ise on lo

Oloye Adebo se alaye fun awon onirohin pe ipade ti on ba ogagun na se laipe yi yori si rere ati pe ori ti ogagun Ironsi ba on so yio ran on lowo pupo ninu ipade ti nwon lo se yi ni ilu Paris

---

# YEYENATU

## Lati Oju Iwe Keji

ke

Olotu: Nibo ni o ni otu tir, si?

Yeyenatu: Se nitoripe nko ni moto? Ti nko ba ni moto larin osu meji oni ki e ma pe mi ni yeye mo

Olotu: Apo melo ni o ni, sile melo papa? Tabi o to pe kebokebo n moto ni?

Yeyenatu: Ha! moto nla nla ko ni pe di meta sile kan. Suuru ni ebo

Olotu: O fe fo ile ni? Tabi Olo jija tun kun iwa buruku re?

Yeyenatu; Iwa buruku te mi ko to tiyin o, Oga.

Olotu: Iwa temi so o ki ngbo?

Yeyenatu; Emi, enitl e fe gbe si ejo ni e nwa

Olotu: Ko da o loju niyen

Yeyenatu: O dara lojo ti emi ati Hassan lo yi Hotel yen, tani gba iya ra ti o wa legbe ti wa?

Olotu: Tabi eni ibi ni iwe abanije obinrin buruku yi

Yeyenatu: Hehen bi o se ri yen Se e ni iwa te mi buru, se emi ko si binu Hen enyin na ma binu ke

Olotu: Sa sora re. Ti mo ba nba o soro iyen ko ni ko ma yaju si tabi egbe ni emi welu re?

Yeyenatu; won Olotu ni enyin nba rin, ki Olorun ma je ki e rin iru irin ti awon Olotu rin sa o

Olotu; Se onisokuso ni o, Sa kuro fun mi

Yeyenatu; Ha! o dabo e ma binu o

---


# KERE O

Nje o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA tose sejade?

Ha! Kosemani ni iwe na je fun omo Yoruba Iwe na kun fun itan Isedale Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti omo re han ninu re.

Mase jeki nwon rohin itan ilu re fun o

3/- pere ni. Postage 9d

Tete f'owo tire ranse si:-

ESAN KOGBOGUN SERVICE

8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria



GBOGBO ARA ILU NKO ORIN IYIN ATI OGO NIPA **DYNAMIREN** TONIKI



ALE-IBI-ALE Egbogi To ki amonu, titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mo daju fun Agbara ati Ajebidan se fun agbalagba Okunrin ati Obinrin gbogbo

Bi are ara ba nmu o, ni gbakugba fun wahala tabi ise sise ti o ko le jeun dara dara, tabi ki o male sun da da de okan losan tabi awon san ara re gbogbo ki se fun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunle daradara won ise tabi wahala sise tabi inu awon ailera gbogbo nyin ti ojo ori (age) ba ti koja ogbon odun si adorin tabi jube lo mo daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfe lati so ara re di otun pata oju re yio si wale re kete alafia ati Igbadun de Bere Dynamiren yi ni Sobu awon i-

Waterloo Medecine Stores
8, Palm Church Street P. O Box 333 Lagos
LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.
ADEDUN CHEMIT
14, Wakeman Street
ATI NI SOBU
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA IBADAN



a successful future means planning **Now!**

Have you planned for the security of your family's future? Start a programme of Life Insurance NOW

*with*

**GREAT NIGERIA INSURANCE Co. Ltd.,**

INCORPORATED IN NIGERIA

Enquire now for full details of our low cost endowment policy.

HEAD OFFICE:

39/41 MARTINS STREET,
P.O. Box 2314, LAGOS
TELEPHONE 25251.

BRANCHES AND AGENTS THROUGHOUT NIGERIA.

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,697 MONDAY FEBRUARY 14, 1966 (2D


## Ọlọṣa Kan fi ẹwọn Ọdun Meji Jura

AKURẸ:– Ni opin ọsẹ to kọja ni Adajọ agba ti Kotu giga ilu Akurẹ paṣẹ pe ki Ọlọṣa kan Yusufu Bauchi ẹni ọdun mẹrinlelogbon yara lọ fi ẹwọn ọdun meje jura lori ẹsun pe ọdaran na lo fọ Ile onile ati pe ọdaran Ọlọṣa na si fi ye Adajọ Agba Ile-ẹjọ giga na Ọgbẹni Samuel Ogunkẹyẹ pe on jẹbi ẹsun ti nwọn ka si on lẹsẹ eyiti iṣe ole jija ati ile fifo.

Ninu awọn ẹlegbẹ Ọlọṣa na ti nwọn fi ye ile-ẹjọ giga na pe awọn ko jẹbi ẹsun ti Ile-ẹjọ giga ka si awọn lẹsẹ ni Mathias Okafor, Abudu, Zaria, Obed Chuknmese, Yesufu Kanlesanwo, Sikiru Kano ati Garuba Portsakuni ni Adajọ Ile-ẹjọ na ba si sun gbigbọ ẹjọ na si ọjọ kẹtadinlogun osu yi.

Ṣiwaju eyi ni Ọlọpa to ba awọn ọdaran na ṣ'ẹjọ ti ṣe alaye niwaju adajọ Ile-ẹjọ na wipe ni ọjọ keje osu karun ọdun to kọja lọ yi ni awọn ọdaran na lo fọ ṣọbu kan ti nwọn si ji awọn ẹru to wa ninu ṣọbu na ko lọ.

Ọlọpa na tun ṣe alaye fun Ile-ẹjọ giga na pe ni ọjọ kanna ni awọn enia na tun lọ fọ ṣọbu ọkunrin kan ti nwọn npe ni Cyril Mberedo ti awọn ọdaran na si ko gbogbo ẹru ti o wa ninu ṣọbu ọkunrin na salọ.

Adajọ Agba ile-ẹjọ giga na ti paṣẹ wipe ki nwọn mu awọn Ọdaran iyoku lọ si itimole titi di ọjọ ketadiulogun osu yi ti Ile-ẹjọ sun gbigbọ ẹjọ na si.

# NWỌN DANA SUN ỌKUNRIN KAN LAAYE

ABEOKUTA:— Ni opin ọsẹ to kọja lọ yi ni agbayanu irohin kan de ile Iṣẹ wa lati ọwọ onirohin wa ti ilu Abẹokuta pe awọn enia kan dina sun Ọgbẹni Sanusi Balogun ti o jẹ ẹlẹri Ijọba fun ẹjọ kan ti Ijọba mba awọn enia mẹta kan ṣe ni kotu kekere ti ilu Abẹokuta eyiti irohin na fi ye wa pe lẹhinti Ọgbẹni Sanusi Balogun gun ori apoti ẹlẹri ti o si sọ ti ẹnu re ni o ba fi ile ẹjọ na sile lati ma pada bọ wa sile.

Irohin tun ṣe afikun pe Ọgbẹni Sanusi Balogun je agbe, o si wa si kotu kekere ti ilu Abẹokuta pẹlu iyawo rẹ lati jẹ ẹlẹri fun Ijọba eyiti o jẹ pe bi on pẹlu iyawo rẹ ti ṣe kuro ni kotu na ni nwọn ba wọ mọto takisi ni ọjọ ọjọ 'Ru ti Iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi lati pada si ile wọn.

Ṣugbọn bi mọto takisi na ti ngbe Ọgbẹni Sanusi pẹlu iyawo rẹ lo ni awọn enia kan ba da wọn duro nibi odo kan ti nwọn npe ni Olomore ti awọn enia na si gbe ọkunrin na kuro ninu mọtọ ti nwọn si gbe salọ sibiti enikan ko mọ ninu igbo kan ti awọn enia na si fi iyawo ọkunrin na silẹ.

Lẹsẹkẹsẹ a ni iyawo Ọgbẹni Sanusi Balogun ba yara lọ si teṣan awọn Ọlọpa lati lọ fi ọran na sun ni pa ohunti oju rẹ ri eyiti Ọga awọn Ọlọpa to wa ni Tesan wọn Ọgbẹni Yerima ati awọn Ọlọp miran pẹlu ohun ija lọwọ ti nwọn si ba obinrin na lọ sibiti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ.

Nigbati ọga awọn Ọlọpa na pẹlu awọn ọmọ lẹhin rẹ de ibiti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ ni nwọn ko bi ri Takisi t o gbe Ọkunrin na pẹlu iyawo rẹ de bẹ.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn ọlọpa na ba bọ sinu igbo ti nwọn si nwa Ọkunrin na kakiri eyiti nwọn fi ri oku Ọkunrin na ninu igbo to wa lẹba ibiti awọn enia na si ti dana sun ọgbẹni Ṣanusi Balogun.

Oniwe irohin wa fi ye wa pe awọn Ọlọpa si ti ri awọn enia mẹta mu ninu awọn enia to ngbe ti abuleko ti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ awọn enia ti awọn Ọlọpa na ri mu ni Rafiu Olude–gun, Isiah Oni, ati Aka ni Salami nwọn si ti mu awọn enia mẹta na lọ si ile ẹjọ kekere ti ilu Abẹokuta eyiti Ọgbẹni Balogun si lọ jẹ ẹlẹri Ijọba lori ẹsun pe awọn enia na ba ile ọgbẹni Sanusi Balogun jẹ ni Sango Ọtta ni ọjọ keji oṣu kini ọdun yi.

Ninu ẹsun ti Ile ẹjọ fi kan awọn enia na ni pe nwọn ji ibon kan eyiti iye owo re je ponun mejidinla ọọta (£48) ati ogbonleni—gb ponun (£230). Ile ẹjọ na si gba iduro awọn enia na

Ninu ọrọ Alakoso eto Irohin fun awọn Ọlọpa Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgbẹni I. W. Esiet fi ye Oniwe irohin wa pe etitọ ni awọn ọna kan dina sun Ọgbẹni Sanusi Balogun, O tun ṣe alaye pe awọn Ọlọpa ti mu enia mẹrin lori ṣẹlẹ to ṣẹlẹ na

## Lati Oju Ewe Kini

o ye lati ma a fi ṣe adajọ ti nwọn yio si ma a ṣe ofin ati idajọ ni ọna ti ofin ba la silẹ fun wọn.

Ni ipari, Ọgbẹni Adekunle Fajuyi tun ṣe alaye wipe, Ijọba Ologun yio tete yara ṣe eto na kiakia, ni ọna ti awọn ara ilu ba nfẹ, ṣugbọn awọn adajọ ti nwọn ba mọ eto Ofin ati Iṣẹ idajọ ni Ijọba Ologun yio yan si ipo awọn adajọ kotu Ijọba Ibilẹ yika gbogbo Ipinlẹ na.

Irohin na sọ wipe, gbogbo awọn adajọ Ile ẹjọ na ko tun gbọdọ de le ẹjọ wọn mọ lati owurọ yi lọ, ki gbogbo wọn parẹ.

O wa sọ wipe, gbogbo ẹjọ ti o wa ni ile ẹjọ wọn ki nwọn ko gbogbo rẹ lọ si ile ẹjọ awọn adajọ agba yika gbogbo Ipinlẹ na, ki nwọn si le pari awọn ẹjọ na nibẹ.

Ọlọla Fajuyi ti sọ wipe iwa ti awọn Ọdọm de Orilẹ ede yi nhu nisisiyi ko dara to rara awọn ko si ni iberu lokan lati ṣe ohun kohun bi o dara tabi ko dara.

O wa rọ gbogbo awọn Odo lati ma a ṣe daada, ki gbogbo won si ma gbe papo gegebi ọmọ iya kanna, ki ifaiyabalẹ le ba wa larin awọn alejo ti nwọn ba da iṣẹ silẹ tabi ti nwọn fẹ ma a gbe Naijiria ni ọjọ iwaju.

## IWA RERE

Ọkan ninu awọn Oniwe Irohin wa sọ wipe Ṣoko bayi ni ni awọn adajọ kotu Ijọba Ibilẹ miran nigbati nwọn gbọ irohin yi.

Ohunti o wa ja awọn enia na laya nisisiyi ni wipe boya ni Ijọba Ologun Iwọ Orun yio tun yan awọn si ipo adajọ mọ, bi ko ba yan awọn si aye na mọ kini awọn yio fi maa jẹun bayi.

# Aṣoju Ijọba

LATI OJU EWE KINI

Ki awọn mejeji to ki ara wọn ti nwọn si dagbere, Ọlọla Dokita Branko Karapandz fun Ọgbẹni Dawodu ni Iwe ififoto pamọ si kan eyiti nwọn ṣe ni ilu Yugoslavia.

Lẹhin eleyi ni awọn mejeji wa gba ara wọn lọwọ ti nwọn si da gbere fun ara wọn pe "O digba.

Aworan ti e nwo niwaju iwe yi ni igbati Ọgbẹni Dawodu nwa ẹbun ti Aṣoju Ijọba na fun un ni ọjọ na.